# Awuyewuye Ifá Lórí Ipò Ọba Láwùjọ Yorùbá

**Ọládélé Caleb Orímóògùnjẹ́**
*Department of Linguistics, African and Asian Studies*
*University of Lagos, Nigeria.*

## Ìfáárà

Tí a kò bá ní pegbá àlapà nígbá lúúrú, tí a kò fẹ́ figbá ọ̀bọ̀rọ́ bẹ̀ha, láwùjọ káàárọ̀-o-ò-jíire-bí, àwọn Ọba ló nilẹ́, ló loko, ló sì ni gbogbo nǹkan tó ń bẹ lókè eèpẹ̀ pẹ̀lú. Ìran Yorùbá gbà pé ẹni bá fojú di Ọba, àwówó yóò wó onítọ̀ún, bẹ́ẹ̀ ló jẹ́ wí pé arọ́bafín lọba ń pa. Kò sí ẹni tó jẹ́ fi ọwọ́ pa idà Ọba lójú, láìdá ara rẹ̀ lẹ́bi. Àwọn tí a gbé iṣẹ́ wọn yẹ̀wò ni Abraham (1946), Fádípẹ̀ (1970), Ojiagbo (1973), Daramọla àti Jeje (1975), Adeoye (1979), Pembarton (1989), àti Drewal, et al. (1989). Adélékè náà ti tú pẹrẹpẹ́rẹ̀ ọ̀rọ̀ lórí ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ láàfin Ọba láwùjọ Yorùbá nípa bó ṣe ń jẹyọ nínú fíìmù àgbéléwò. Yàtọ̀ sí èyí, àbájáde àbọ̀ oko ìwádìí ló pọ̀jù nínú iṣẹ yìí. Nínú pépà yíì, a fẹ́ kí a mọ ipò Ọba láyé àtijọ, báwo ni ipò Ọba lóde-òní, iṣẹ́ wọn àti èèwọ̀ wọn. Bákan náà ẹ̀wẹ̀, ó yẹ ká mẹ́nuba àwọn nǹkan tí Ọba ń lò bí aṣọ, adé, ìrùkẹ̀rẹ̀, ìlẹ̀kẹ̀, àkún ọwọ́ àti tẹsẹ̀, ọ̀pá àṣẹ, ìtẹ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Pépà yìí jẹ́ ká mọ̀ pé àwọn nǹkan-èlò wọ̀nyí ní iṣẹ́ tí wọ́n ń jẹ́ fún àwùjọ. Iṣẹ́ yìí lo tíọ̀rì ìmọ̀ ìlò-àmì láti ṣàlàyé àwọn nǹkan-èlò Ọba tí a mẹ́nubà lókè yìí. Ìdí tí a fi yan tíọ̀rì yìí láàyò ni pé òun ló ṣeé ṣàlàyé iṣẹ́ ọnà ajẹmárokò dáadáa. Ògúndèjì (1997) náà lo tíọ̀rì yìí láti fi tú àrokò Yorùbá palẹ̀. Ẹni tó dá tíọ̀rì yìí sílẹ̀ ni ará America kan tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Charles Sanders Pierce, tí Ferdinand de Saussure sì jẹ́ Amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ rẹ̀. Olùdásílẹ̀ tíọ̀rì ìlò-àmì yìí pín in sọ́nà mẹ́ta:

(i). àmì ìbáṣepọ̀ à-ṣedúró-fún (iconic mode),

(ii). àmì ìbáṣepọ̀ atọ́ka ìṣẹ̀lẹ̀ (indexical mode) àti
(iii) àmì ìbáṣepọ̀ apàrokò (symbolic mode).

Ní ìbámu pẹ̀lú ìpínsísọ̀rí olùdásílẹ̀ tíọ́rì yìí, àmì ìbáṣepọ̀ apàrokò tó lè ṣe ìtúpalẹ̀ iṣẹ́-ọnà ajẹmárokò dunjú ni a óò fi ṣe ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀ fún pépà yìí.

**Ipò Ọba Láwùjọ**

Gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe mọ̀ tẹ́lẹ̀ pé ipò ọlá, iyì, ẹ̀yẹ, àpọ́nlé, àrà, ìgajàbùkù, kò-ṣeé-gbéná-wojú-wò àti ọ̀wọ̀ ni a máa ń bá àwọn oba ilẹ̀ Yorùbá. Ọjọ́ tí ẹnìkan bá ti jọba náà ló ti ṣoògùn àṣegbé, ìdí rèé tí wọ́n fi n pè wọ́n ní Kábíyèsí, tó túmọ̀ sí 'ká-bi-í-kò-sí'. Nínú odù Ọ̀sáyẹ̀kú, a rí pàtàkì Ọba tó fi jẹ́ pé kò sí ẹni tó ń yẹ Ọba lọ́wọ́ nǹkan tó bá ṣe wò:

*Ẹja ńlá gbénú omi yọrí.*
*Àbàtà ńlá wẹ̀wù àlà kanlẹ̀.*
*Àmù ńlá abẹnu gbọ́ngangbọ̀ngan.*
*A díá fỌ́ba tí ń bẹ ní àgbàkẹ́mù ayé*
*Ẹbọ wọ́n ní kó rú,*
*Ẹbọ wọ́n ní kó ṣe.*
*Ẹnu kì í jí kó má run orín sàlùlù.*
*Ẹ jẹ́ ká fi ọ̀rọ̀ Ọba pọ̀sọ́lọ.*
*Àgbasà dé o!*
*'Mọnígìrìgìrì.*
*Àtikú,*
*Àtàrùn,*
*Wọn a sì rỌ́ba sá.*[1]

Ìtàn tí ó rọ̀ mọ́ Odù yìí sọ pé nígbà ìwáṣẹ̀, Ọba kan wà láàrin ọ̀tá débi pé gbogbo Olóyè ìlú dìtẹ̀ mọ́ ọn, wọ́n sì yọ ọ́ lóyè. Lẹ́yìn

èyí, ìlú kò rójú, fíofío mule ayé, dùgbẹ̀-dùgbẹ̀ móde ọ̀run, bẹ́ẹ̀ ní igbá orí àmù kò lura wọn. Ọba rúbọ tí wọ́n ní kó rú. Kò pẹ́, kò jìnnà, ni Èṣù lọ kó sínú ọmọ Olóyè Ọ̀tún débi pé ó lọ jalè. Olóko mú un wá sí ìlú fún ìdájọ́. Nígbà tí wọ́n ní kí ọmọ Ọ̀tún sanwó ìtanràn, Ọba tí wọ́n yọ lóyè ló bá wọn san owó ìtanràn náà. Èyí mú kí wọn dá Ọba padà sórí oyè. Ẹ̀kọ́ tí a rí fàyọ nínú ìtàn yìí ni pé, ìlú kò le tòrò tí kò bá sí Ọba.

Èké ló dáyé tí aásà di àpòmu tí àwọn Ọba fi ń wà lábẹ́ 'gómìnà'. Ẹ wá jẹ́ ká mọ̀ pé kì í tán nínú igbá osùn ká má rí èyí tí a ó fi pa ọmọ lára, àṣẹ àtijọ́ sì ń bẹ lẹ́nu àwọn Ọba ilẹ̀ Yorùbá. Èyí mú wa ránti ìtàn Aláàfin Ọ̀yọ́ àti Òyìnbó Ajẹ́lẹ̀ tí wọ́n jọ fi ìpàdé sí aago mọ́kànlá àárọ̀ ọjọ́ kan. Aago mọ́kànlá gan-an ni Aláàfin ṣẹ̀ṣẹ̀ jí, ó múra láti pàdé Ajẹ́lẹ̀. Kó tó kan Ajẹ́lẹ̀ lára, aago mẹ́ta ọ̀sán ti lù. Inú bí Ajẹ́lẹ̀, ó sì béèrè pé kí ló dé tí Aláàfin kò dé láago mọ́kànlá ní ìbámu pẹ̀lú àdéhùn wọn. Aláàfin dá a lóhùn pé nígbà tí Aláàfin bá dé náà ni aago mọ́kànlá lù, èyí tó fihàn pé Ajẹ́lẹ̀ àti àwọn ènìyàn rẹ̀ gbọdọ̀ máa dúró de òun Aláàfin ni, Ọba ṣáà ló nilẹ̀, ó sì ba lórí ohun gbogbo ni.

## Ìlú Ṣíṣe Láyé Àtijọ́

Láyé àtijọ́, kí àwọn aláwọ̀ funfun tó gòkè odò, àwọn Ọba ló ni kòkáárí ètò ìṣèlú lọ́wọ́. Ẹjọ́ tí Baálé bá parí tì, yóò dé ọ̀dọ̀ Olóyè àdúgbò; tí Olóyè àdúgbò kò bá rójútùú rẹ̀, ọ̀dọ̀ Ọba ni yóò parí sí. Tó bá sì jẹ́ ìletò ni, tí Baálẹ̀ bá parí rẹ̀ tì, Ọba ni yóò yanjú ọ̀rọ̀ náà. Ọba ni Olórí ìlú àti àwọn ìgbèríko. Baálẹ̀ àti àwọn Olóyè ìlú pátápátá ló wà lábẹ́ rẹ̀. Títí dayé ọ̀làjú tí a wà yìí, Gómìnà gbọdọ̀ kọ́kọ́ rí Ọba kí ó tó lè rí ará ìlú, bíi bẹ́ẹ̀ kọ́, èdè-àì-yédè yóò bẹ́ sílẹ̀. Ọba ló ń fi Olóyè agboolé, àdúgbò àti

ìgbèríko kọ̀ọ̀kan jẹ, tí yóò sì jẹ gàba lé wọn lórí. Ọ̀kan ni Ọba gbọdọ jẹ́ ní ìlú kan, àwọn ìjòyè ló máa ń pọ̀, Ọba ló sì ń kó gbogbo wọn jẹ̀.

**Èèwọ̀ fún Ọba**

Nnkan tí a kò gbọdọ̀ ṣe náà ní wọ́n ń pè ní èèwọ̀. Tọmọdé tàgbà, ọkùnrin, obìnrin, ọlọ́lá, òpìjẹ̀, tỌba tÌjòyè ló ní nǹkan tí a kì í ṣe. Gbogbo wa la mọ̀ pé kò sẹ́ni tó ga ju àbùkù lọ, àfẹni tó bá bẹ̀rẹ̀ lábẹ́ rẹ̀. Ọba ìlú kọ̀ọ̀kan láwùjọ Yorùbá ló ní èèwọ̀ tí kò gbọdọ̀ tàpá sí. Bí àwọn afọbajẹ bá ti ń ṣètò àtigbé ọba gorí oyè ni wọn yóò ti jẹ́ kí ó mọ àwọn nǹkan tí kò gbọdọ̀ dánwò. Wọ́n á sì sọ àtubọ̀tán èèwọ̀ kọ̀ọ̀kan. Nínú ìtàn, a gbọ́ pé ẹ̀dá bí ènìyàn ni èèwọ̀ jẹ́ ní ìgbà ìwáṣẹ̀ ní ìbámu pẹ̀lú bó ṣe hànde nínú Odù Ìdinbàrà:

*Ìdinbárádin.*
*Ìdinbàràdin.*
*Ìdin òkú ìgbín,*
*Sá gburu gburu jáko.*
*A diá fún Èèwọ̀,*
*Tíí ṣọmọ Elédìdímòre,*
*Níjọ́ tí ń ti ọ̀run bọ̀ wá sílé ayé.*
*Wọ́n ní ó kárálẹ̀ ó jàre,*
*Ẹbọ ni kó máa ṣe.*
*Ó sì gbẹ́bọ níbẹ̀, ó rúbọ.*
*Ó gbéèrù,*
*Ó tèèrù.*
*Àtèwe,*
*Àtàgbà,*

*Èèwọ̀ kì í fini í sùn,*
*Tí fi í pani*[2]

Nígbà tí Èèwọ̀ ń bọ̀ láti òde ọ̀run, wọ́n ní ayé yóò san án. Wọ́n ní bó rúbọ bí kò rúbọ, ọmọ aráyé yóò jẹ ẹ́. Wọ́n ní ṣùgbọ́n kó rúbọ kí ó bàá lè máa hun ẹnikẹ́ni tó bá jẹ ẹ́. Èèwọ̀ rú gbogbo ẹbọ tí wọ́n yàn fún un. Láti ìgbà náà ló ti di pé èèwọ̀ ń hun ẹni tó bá jẹ ẹ́. Èèwọ̀ kò yọ ẹnikẹ́ni sílẹ̀. Ẹran ọ̀hun ni èèwọ̀ jẹ́, ẹní bá fọwọ́ pa idà rẹ̀ lójú, yóò dá ara rẹ̀ lẹ́bi. Nǹkan tó jẹmọ́ èèwọ̀ tí Ọba kò gbọdọ̀ ṣe pọ̀ rẹpẹtẹ, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé díẹ̀ ni a óò mẹ́nu bà nínú wọn.

**Ilẹ̀-dídà**

Èèwọ̀ ló jẹ́ fún Ọba láti dalẹ̀ ọmọ aráyé, àwọn Òòṣà, ajogun, òkú-ọ̀run àti àwọn Olóòfiri ará-odò-alẹ̀. Bẹ́ẹ̀ náà ni wọ́n kò gbọdọ̀ dalẹ̀ Ọ̀rẹ́ wọn. Ẹ jẹ́ ká gbọ́ ọ̀rọ̀ ẹnu Odù Ọ̀yẹ̀kúwọ̀n-ọ́n-rín níbi tó ti sọ ìtàn Ọ̀rúnmìlà tó jẹ́ Ọba láàrin àwọn Ìbọ yòókù. Ó dalẹ̀ Èṣù ọ̀rẹ́ rẹ̀, bó tilẹ̀ jẹ́ pé kò mọ̀, síbẹ̀, ayé kò rójú, àfìgbà tí wọ́n bẹ Èṣù:

*Emi lọpọ́n fi ṣe yín,*
*Tẹ́ẹ fi gbá ṣẹ́rin mọ́pọ́n létí.*
*A díá fún Ọ̀rúnmìlà,*
*Baba kò mọ èèwọ̀,*
*Yóó máa jẹ àdín.*
*Ẹbọ wọ́n ní kí baba ó máa ṣe.*
*Àwa ti sá fún èèwọ̀,*
*Ire àwá sì bá wa délé kokooko.*[3]

Ọ̀rúnmìlà tó jẹ́ Ẹ̀dú Ọlọ́jà láàrin àwọn Ìbọ jẹ́ ọ̀rẹ́ Èṣù, ọ̀dọ̀ ìyá Èṣù tún ni Ọ̀rúnmìlà gbé dàgbà. Ọ̀rúnmìlà ti bá Èṣù mulẹ̀ pé òun yóò máa pa òfin rẹ̀ mọ́. Kò pẹ́, kò jìnnà, ilé ayé bẹ̀rẹ̀ síí dàrú. Wọ́n ní Ọ̀rúnmìlà ló dalẹ̀ ọ̀rẹ́. Ọ̀rúnmìlà ní ọ̀rẹ́ wo ni. Wọ́n ní Èṣù ni, òun ló sì ń da ilé ayé rú nítorí pé inú ń bí i gan-an ni. Ọ̀rúnmìlà ti gbàgbé pé òun máa ń fàdín ṣètùtù, ó ń fi wúre láràárọ̀. Bẹ́ẹ̀ sì rèé, àdín ni orúkọ iyá Èṣù. Èṣù kì í jẹ àdín nítorí pé ó n bọ̀wọ̀ fún ìyá rẹ̀. Nígbà náà ni Ọ̀rúnmìlà rúbọ, tó sì bẹ Èṣù kí ayé tó lè rójú. Ẹ̀kọ́ tí a fẹ́ fà yọ ni pé Ọba kò gbọdọ̀ dalẹ̀ ará ìlú àti àwọn Òǹnilẹ̀ kí ìlú bàá lè tòrò bí omi a fòórọ̀ pọn.

**Ojúkòkòrò**

Ọ̀hun ni ojúkòkòrò jẹ́ fún ẹ̀dá adáríhurun, kódà kò yọ Ọba sílẹ̀. Àbùkù ńlá gbáà ló máa ń fà bá ènìyàn láwùjọ. Gbogbo nǹkan tó wà ní àwùjọ jẹ́ dúkìá fún Ọba. Gbogbo wa la mọ̀ pé a kì í gbọ́ 'gbé-rù-mí ní ààfin, 'sọ̀-mí' nìkan la lè gbọ́. Kò sẹ́ni tí kò mọ̀ pé 'ojú ló ń kán ọmọ olè tó ń dájọ, gbogbo èyí tí àwọn aládùúgbò dá ṣe bí baba rẹ̀ ni yóò kó o. Odù Ìrosùn-méjì sọ̀tàn Ọba olójúkòkòrò kan báyìí:

*Ọsán já ọrún dọ̀pá.*
*Okùn já èdìdì ọwọ̀.*
*Àkàtàmpó jákùn ó dọ̀gọ.*
*A diá fún Ìkookò,*
*Tí wọn yóó fi joyè Olúùgódó,*
*Tí wọn yóó fòṣììrì yọ ọ́ lóyè…*[4]

Ìkookò jẹ Ọba ìlú Ìgódó, wọ́n kìlọ̀ fún un pé kò gbọdọ̀ mú nǹkan onínǹkan, ṣùgbọ́n kò gbọ́. Bí Ìkookò ṣe ní ojúkòkòrò tó,

bó ṣe ń jí ẹran lọ́wọ́ àgbà ló ń jí lọ́wọ́ ọmọdé. Nígbà tí ọ̀rọ̀ rẹ̀ sú ará ìlú, wọ́n gbìmọ̀ pọ̀, wọ́n yọ́ ọ lóyè. Èyí ń fi yé wa pé gbogbo alágbára àti aláṣẹ gbọdọ̀ mojú mọra nínú ìhùwàsí wọn. Oúnjẹ 'kòtọ́' kò gbọdọ̀ yà sí sàkání Ọba.

## Mímọ̀ Àṣà Dunjú

Nǹkan mìíràn tó jẹ́ kò-seé-mọ́-nì-ín fún Ọba ni àṣà ìbílẹ̀. Kì í ṣe pé Ọba kò gbọdọ̀ mọ àṣà ilẹ̀ mìíràn, ṣùgbọ́n àṣà àkọ́kúntẹni ló yẹ kó jẹ́ fún àwọn Ọba ilẹ̀ Yorùbá. Oríṣiríṣi àwọn nǹkan tó jẹ́ àkóónú àṣà ni èdè, ẹ̀sìn àti àwọn nǹkan ìṣẹ̀mbáyé mìíràn. Bí ènìyàn bá sọlé nù, a sọ̀wà nù. Ẹní bá sì sọ̀wà nù ti so àpò ìyà kọ́ ní ìbámu bó ṣe hànde nínú Ifá:

*Ìpọ̀ntí ajá jìn-un jìn-un*
*Babaláwo ajá ló ṣefá fájá*
*Nígbà tájá ó sọlé nù*
*Tí ó sàpò ìyà kọ́*
*Ìgbà tí ajá sọlé nù,*
*Igbe lajá ń ké kiri.*[5]

Kò yẹ kí àwọn Ọba gba àṣà ilẹ̀ òkèèrè kanrí débi pé àṣà ìbílẹ̀ tiwọn yóò di igbá ìkólẹ̀. Ṣé ó tọ́ kó wá jẹ́ pé ẹni a bí wọn mọ́ kì í wù wọ́n, ẹni ẹlẹ́ni níí yá wọn lára. Ẹ jẹ́ ká kọ́kọ́ gbọ́rọ̀ ẹ̀sìn yẹ̀wò. Ẹní bá mọ tìfun tẹ̀dọ̀ ẹ̀sìn ìbílẹ̀ Yorùbá, yóò mọ bí ó ṣe yẹ kó to ìlú nípa mímọ ohun tó tọ́ àti èyí tó yẹ láwùjọ àṣùwàdà ènìyàn. Kí aláwọ̀ funfun tóó dé ni Yorùbá ti ní ẹ̀sin tiwọn, tí wọ́n sì mọ̀ pé Ọlọ́run wà. Ẹ ẹ̀ gbọ́ bí Ògúndáborógbè ti wí:

*Ibi a gbé dá ògúndáborógbèé'lẹ̀*
*Ọmọ awo a fẹ́ẹ́ jẹ,*

*Ọmọ awo a fẹ́ẹ̀ mu,*
*Ọmọ awo a fidí ọ̀rẹ̀rẹ̀ balẹ̀.*
*Ó dífá fún Olódùmarè,*
*Ọmọ a-ṣohun-rabata-kárí-ayé.*
*Kò sóhun t'Ọ́lọ́run ò leè ṣe.*
*Bó ṣòjò*
*A ṣọ̀dá*
*A ṣèkan bí otútù*
*A ṣèkan a mú bí ọyẹ́*
*Kò sóhun t'Ọ́lọ́run ò leè ṣe*[6]

Tí a bá wo ẹsẹ-Ifá òkè yìí dáadáa, a óò rí i pé ìran Yorùbá ti mọ̀ pé Ọlọ́run wà láti ìgbà ìwásẹ̀ àti pé kò sí ẹ̀dá tó ju Olódùmarè lọ. Ìdí rèé tí ọpọ̀ ẹsẹ-Ifá fi n parí báyìí:

*…ló n máa tẹ́bọ rú*
*Wọ́n ní wọn kì í tẹ́bọ rú,*
*Aláwo ni wọ́n n yìn,*
*Aláwo á wá yin Ifá,*
*Ifá á wá yin Elédùmarè Ọba.*
*Èdùmàrè nìkàn ló mẹnì tí yóó yìn.*[7]

Wàhálà tó pọ̀ ni àìkọbiara sí àṣà ẹni máa ń kó báni. Tí a bá wo ìtàn Ayélẹ̀gún tó kọ ìṣẹ̀ṣe sílẹ̀ nínú Odù Òtúrá-oríkọ̀, ó kó ìdààmú bá ara rẹ̀ àti ará ìlú:

*Baba mórí balẹ̀,*
*N ò mórí balẹ̀.*
*Ilá mórí balẹ̀,*
*Ilá kó.*

*Baba mórí balẹ̀,*
*N ò mórí balẹ̀.*
*Ikàn mórí balẹ̀,*
*Ó wẹ̀wù ẹ̀jẹ̀.*
*Baba mórí balẹ̀,*
*N ò móri balẹ̀*
*Àgbáǹréré mórí balẹ̀,*
*Ó yọ̀wo lórí ṣanran sanran.*
*A dífá f'un Ayélẹ̀gún,*
*Tí ó sọdè rẹ̀ nù,*
*Tí gbogbo ayé yóó ma bá a wá a kiri…*[8]

Yàtọ̀ sí ẹ̀sìn, èdè tún ṣe pàtàkì nínú àṣà Yorùbá. Ọba gbọdọ̀ mọ àpadé àludé èdè Yorùbá. Kò pọ́n Ọba lé kó má lè sọ̀rọ̀ kó yọ kòmóòkun rẹ̀ pẹ̀lú èdè Yorùbá. Ẹ jẹ́ ká wo Odù-elédè láti le mọ bí èdè ti ṣe pàtàkì tó gẹ́gẹ́ bí irinṣẹ́ fún Ọba láti fi ṣèlú:

*A kì í bọ Eégún láìlọ́tí*
*A kì í bọ Òòṣà láìlóbì*
*A kì í bọ Ṣàngó láìlórógbó*
*Bẹ́ẹ̀ ni a kì í bọ Ifá láìlọ́pọ̀lọpọ̀ eku òun ẹja*
*A dífá fún Ọ̀rúnmìlà*
*Lọ́jọ́ tí òun àti Ọ̀sanyìn Bààwẹ̀*
*Lọ rèé wádìí ayé…*[9]

Ìtàn sọ fún wa pé nígbà tí Ọ̀rúnmìlà àti Ọ̀sanyìn ń lọ sí ọ̀run láti wádìí ayé, ní agbede méjì ayé òun ọ̀run ni wọ́n ti pàdé Èdè tó jẹ́ oníbodè. Ó sọ fún wọn pé òun Edè ló lè bá wọn wádìí gbogbo ohun tó wà lóde ìsálayé. Èdè ló kọ́ wọn ní oríṣiríṣi nǹkan àṣírí tó

wà nílé ayé. Ọba tó bá gbọ́ èdè Yorùbá dáadáa yóò le ṣe àkóso àwọn ènìyàn rẹ̀ láìfigbá kan bọ̀kan nínú.

### Pípárí Aáwọ̀ Láàrín Ìlú

Iṣẹ́ Ọba ni láti rí i pé kò sí gbọ́nmi-sí-i-omi-kò-tó nílùú. Ọba kò gbọdọ̀ ṣe ojúṣàájú. Tí ìjà bá wà láàrin ẹgbẹ́ olóṣèlú, ó yẹ kí ọba lè parí rẹ̀. Aṣọ̀tún-ṣòsì-má-babì-kan-jẹ́ ló yẹ kí Ọba jẹ́ láàrin ìlú. Ọba kò gbọdọ̀ fara mọ́ ẹgbẹ́ òṣèlú kan ju àwọn yòókù lọ, nítorí pé òun ni baba gbogbo wọn. Irúfẹ́ ìwà báyìí ló lè jẹ́ kí nǹkan máa lọ ní ìrọwọ́rọsẹ̀ láwùjọ Yorùbá.

### Ìmúra Ọba

Yorùbá bọ̀ wọ́n ní ìrínisí ni ìsọnilọ́jọ̀. Ìmúra Ọba máa ń bu iyì kún wọn gan-an ni. Ìdí tí Ọba fi gbọdọ̀ máa múra nípa aṣọ gidi wíwọ̀ la rí nínú odù Ọ̀ṣẹ́logbè tó sọ ìtàn ọba kan tí ó jẹ́ni pàtàkì, ṣùgbọ́n tí kì í múra dáadáa, tí wọ́n wáá fẹ̀gbin lọ̀ ọ́ nígbà tó ràjò:

*Tí wọ́n bá rìnrìn ìyà,*
*Tí wọ́n mójú ìṣẹ́ wọ̀lú,*
*Ojúkójú ni wọ́n fi ń wò wọ́n,*
*Ẹníkẹ́ní ni wọ́n ń tẹ́ fún wọn,*
*Igbákígbá ni wọ́n fi ń bomi fún wọn.*
*A dífá fún Ọlọmọnìnì tí ń lọ sóde Ìwéré.*
*Ọlọmọnìnì,*
*Ọlọmọnìnì.*
*Ìrí tó o rí la rúbọ rẹ.*
*Ọlọmọnìnì jọ̀wọ́.*[10]

Ìgbà tí Ọlọmọnìnì tún padà lọ sí ìlú Ìwéré pẹ̀lú ìmúra tó jojú ní gbèsè ni wọ́n tó kà á sí ènìyàn pàtàkì. Ìmúrasí ni ìsọnilọ́jọ̀. Gbogbo nǹkan tí àwọn Ọba ń lò ló ni ìtumọ̀. Àwọn nǹkan tí Ọba ń lò ni adé, ìlẹ̀kẹ̀, àkún, aṣọ agbádá, ìrùkẹ̀rẹ̀, ọ̀pá, bàtà, ìtẹ́, ẹṣin àti bẹ́ẹ̀ lọ. Àwọn abẹ́nà wa lóko ìwádìí sọ nǹkan tí àwọn nǹkan-èlò wọ̀nyí dúró fún. Adé ni wọ́n fi ń mọ Ọba láwùjọ Yorùbá. Adé ló dúró gẹ́gẹ́ bí Ọba, òun gan-an ni wọ́n ń bu ọlá fún. Ó dúró gẹ́gẹ́ bí ààbò lórí ìlú. Ó dúró fún ìbẹ̀rù, àṣẹ àti ọ̀wọ̀ fún ipò Ọba láàrin àwọn ènìyàn. Ìlẹ̀kẹ̀ ni Ọba ń fi sọ́wọ́, tí àkún sì jẹ́ ẹ̀ṣọ́ tí wọ́n ń fi sọ́rùn. Yàtọ̀ sí ẹwà tí wọ́n ń bù kún Ọba, okùn tí a fi so wọ́n pọ̀ dúró fún Ọba tí àkún àti ìlẹ̀kẹ̀ sì dúró gẹ́gẹ́ bí ará ìlú tí Ọba so pọ̀. Bí ènìyàn ṣe ń tọ́jú ìlẹ̀kẹ̀ àti àkún náà ni ó yẹ kí Ọba máa ṣe ìtọ́jú gbogbo ènìyàn tó wà lábẹ́ àkóso rẹ̀. Òwe Yorùbá sọ pé ayé tí ẹṣin kò jẹ, ìrù ìdí rẹ̀ yóò jẹ́ é. Ìtumọ̀ rẹ̀ ni pé yóò yẹ Ọba, Ìjòyè, àti àwọn ará ìlú ju bó ṣe yẹ àwọn tó bí wọn lọ. A tún lè sọ pé ayé ìlú yóò máa dùn ju ti àtẹ̀yìnwá lọ. Ìtumọ̀ mìíràn tó tún gbé jade ni pé ará ìlú kò níí kú ní rèwerèwe. Ìdí rèé tí wọ́n fi n sọ pé ìrùkẹ̀rẹ̀ Ọba yóò jẹ kù bí okinni.

Àwọn ọba máa ń lo ọ̀pá láti fi hàn pé ipò àgbà ni àwọn wà. Bó ti wù kí ọba kéré lọ́jọ́ orí tó, ipò àgbà ló wà, òun sì ni baba gbogbo ará ìlú. Aṣọ tí àwọn Ọba ń wọ̀ máa ń bu iyì kún wọn. Aṣọ Ọba ni wọ́n ń pè ní mọ́sàajì, aṣọ Ọba tó koná yanran yanran. Bí aṣọ ṣe ń bo àṣírí ara ni Ọba yóò máa bo àṣírí ará ìlú ni èyí túmọ̀ sí. Láyé àtijọ́, òrìṣà gbé mi látèté mi kò ju orí ẹṣin lọ. Ẹṣin ni àwọn Ọba ń gùn láyé àtijọ́. Ẹṣin kì í wáyé kó má dẹni àpésìn. Àwọn ènìyàn ló ń pako fún ẹṣin jẹ, èyí ló fi yàtọ̀ sí ẹran ilé yòókù. Ìdí rèé tí àwọn Ọba fi ń di ẹni tí gbogbo ènìyàn ń sìn. Orí ìtẹ́ ni Ọba máa ń gúnwà sí. Èyí gan-an ni wọ́n fi ń sọ pé ẹnìkan jọba. Tí

wọ́n bá sọ pé ẹnìkan gorí ìtẹ́, ó túmọ̀ sí pé ẹni náà jọba. Ìtẹ́ dúró fún ọlá, ọlà, iyì, àpọ́nlé, ẹ̀yẹ àti agbára àjogúnbá tí àwọn aráajọ́un gbé kalẹ̀. Gbogbo àwọn nǹkan wọ̀nyí ló so mọ́ Ọba lára tí ó fi di àléèbá láàrin ìlú.

## Àgbálọgbábọ̀

Nínú atótónu wa, a rí i pé àwọn Ọba ilẹ̀ Yorùbá ń ṣe iṣẹ́ takun takun láti lè ṣe àkóso ìlú. Àwọn Ọba ni àtàrí tí kò jẹ́ kí oòrùn pa àgbọ̀n ìsàlẹ̀ àṣà Yorùbá. Lọ́rọ̀ kan, a lè sọ pé àwọn Ọba ni ó ń ṣe àkóso lọ́nà tó tọ́ àti lọ́nà tó yẹ nílẹ̀ káàárọ̀-o-ò-jíire. Pépà yìí jẹ́ ká mọ àwọn nǹkan tó buyì àti èyí tó tàbùkù Ọba láwùjọ Yorùbá. Ẹ̀wẹ̀, àrokò tí àwọn nǹkan àmúlò Ọba ń pa sí àwùjọ Yorùbá ni pépà yìí tú yẹ́bẹ́yẹ́bẹ́. Láìdéènà pẹnu, pépà yìí jẹ́ gẹ́gẹ́ bí aránnilétí àṣà fún àwọn Ọba ilẹ̀ Yorùbá.

## Ìtọsẹ̀-ọ̀rọ̀

1. Ní ọdún 2012 ni gba ẹsẹ-Ifá yìí lọ́wọ́ Ìyánífá Fáfú-un-kẹ́ Ọlátińwọ̀ ní ìlú Èkó.
2. Ọwọ́ arabìnrin yìí náà la ti gba ẹsẹ-Ifá yìí lọ́dún kan náà.
3. Ọ̀dọ̀ rẹ̀ náà la ti gba èyí.
4. Láti ọwọ́ Awo Adébóyè Fátóògùn la ti gba ẹsẹ-Ifá yìí lọ́dún 1984 lágboolé Ọba, Òkèkere nílùú Ìlobùú ní Ìpínlẹ̀ Ọ̀ṣun.
5. Awo Adémọ́lá Fábùnmi ní ìlú Ìwàyà ti Ìpínlẹ̀ Èkó ló fún wa ní ẹsẹ-ifá yìí lọ́dún 2012.
6. Láti ọ̀dọ Awo Ẹgbẹ́róngbé ni a ti ṣalábàápàdé ẹsẹ-Ifá yìí níbi ọdún Ifá ti Ìjọ Ọ̀rúnmìlà Àtò lÉkòó lọ́pọ̀ ọdún díẹ̀ sẹ́yìn.
7. Àyọlò yìí ni àwọn babaláwo ṣábà máa ń lò láti kádìí ẹsẹ-Ifá kíkì.
8. Ọ̀jọ̀gbọ́n Wándé Abímbọ́lá ló ki ẹsẹ-Ifá yìí ní yàrá ìgbẹ̀kọ́ nígbà tí mo jẹ́ akẹ́kọ̀ọ́ ní ọdún 1982 ń Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀ tí a mọ̀ sí University of Ifẹ̀ nígbà náà.

9. Àyọlò yìí jáde nínú pépà tí Ọ̀jọ̀gbọ́n Ọlásọpé Oyèláràn kà níbi ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ní ìrántí J.F. Ọdúnjọ ní ọgbà Yunifásítì Ìbàdàn ní ọdún 1984.
10. A gba ẹsẹ-Ifá yìí ní ọdún 2012 láti ọwọ́ Awo Adémọ́lá Fábùnmi.

## Ìwé Ìtọ́kasí


Abraham, R. (1946). *Dictionary of Modern Yorùbá.* London: Holder and Stoughton.

Adélékè, D. (2006). "Communication from the Court Reflection in the Yorùbá Video Film" in *Africarecistago Centre de Estudes Africanos.*

Adeoye, C. (1979). *Àṣà àti Ìṣe Yorùbá.* Ibadan: Oxford University Press.

Daramọla, O. & Jeje, A. (1975). *Àwọn Àṣà àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá.* Ibadan: Onibọnoje Press.

Drewal, H. et al. (1989). "Nine Countries of African Art and Thought" *African Arts, Vol. 23, No: 68-77.*

Fádípẹ̀, N. (1970). *The Sociology of Yorùbá*. Ìbàdàn: Ìbàdàn University Press.

Ferdinand de Saussure (1978). *Course in General Linguistics, London.*

Ògúndèjì, A. (1997). "The Communicative and Semiotic Contexts of Àrokò among the Yorùbá Symbol Communication Systems" in *African Languages and Cultures,* School of Oriental and African Studies, University of London, Vol. 10, No. 2: 145-156.

Ojigbo, A. (1973). "Conflict Resolution in the Traditional Yorùbá Political System" *Cahiers Africaine, Vol. 13 Cahiers 50:275-292*

Oyelaran, O. (1984). ‘’Ìtàn Ìdàgbàsókè Èdè Yorùbá’’ níbi Àpérò Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ní ìrántí J.F.Ọdúnjọ ní University of Ìbàdàn.

Ọláwuyì, O. (2011). *Àkójọpọ̀ Ẹ̀ẹ́dẹ́gbaàje Òwe àti Àṣàyàn Ọ̀rọ̀*. Lagos: Multiple Dee Ltd.

Peirce, C. (1883). *Studies in Logic, by Members of The Johns HopkinsUniversity, ed.* Boston: Little Brown.

Pemberton, J. (1989). “Art and Ritual for Yorùbá Sacred kings” *Art Institute of Chicago Museum Studies, Vol. 15, No. 2: 96-111.*